# OPIN IṢẸ́ PAULU NI ASIA

## Iṣe Awọn Apọsteli 20:1-38

## ẸKỌ 347 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Emi kò kà ẹmi mi si nkan rara bi ohun ti o ṣọwọn fun mi, ki emi ki o ba le fi ayọ̀ pari ire-ije mi, ati iṣẹ-iranṣẹ ti mo ti gbà lọdọ Jesu Oluwa, lati mã ròhin ihinrere ore-ọfẹ Ọlọrun" (Iṣe Awọn Apọsteli 20:24).**

**I Irin-ajo Paulu lati Efesu si Kọrinti ati Ipadabọ si Troasi**

1 Paulu gba ilu Troasi lọ si Makedonia lẹyin irukerudo ti o ṣẹlẹ ni Efesu, Iṣe Awọn Apọsteli 20:1; 2 Kọrinti 2:12, 13

2 O wá si Kọrinti ni ilẹ awọn Hellene, Iṣe Awọn Apọsteli 20:2

3 O pada bọ̀ si Troasi, Iṣe Awọn Apọsteli 20:3-6

**II Irin-ajo Paulu lati Troasi si Miletu**

1 Eutiku ṣubu lati oju ferese òke-kẹta ni akoko iwaasu Paulu, Iṣe Awọn Apọsteli 20:7-9

2 A dá ẹmi rẹ̀ pada, Iṣe Awọn Apọsteli 20:10-12

3 Paulu rin irin ajo lọ si Miletu, Iṣe Awọn Apọsteli 20:13-17

**III Ọrọ-iyanju Paulu si awọn Alagba ni Efesu**

1 O rán awọn alagba leti nipa iwaasu ati ẹkọ irẹlẹ ti o ti fi kọ́ wọn, Iṣe Awọn Apọsteli 20:18-21; Titu 2:7, 8

2 Oun kò kábamọ lilọ kuro nibẹ, Iṣe Awọn Apọsteli 20:22-27; 2 Timoteu 4:7

3 A gba awọn alagba niyanju lati bọ́ agbo Kristi, a si kilọ fun wọn nipa awọn eniyan buburu, Iṣe Awọn Apọsteli 20:28-32; 2 Timoteu 3:1-5; 2 Peteru 2:1-3

4 Aini ojukokoro Paulu jẹ́ apẹẹrẹ fun gbogbo eniyan, Iṣe Awọn Apọsteli 20:33-35; 1 Samuẹli 12:3

5 O fi adura pari iwaasu rẹ̀, Iṣe Awọn Apọsteli 20:36-38

### ALAYE

**Ẹmi Itankalẹ Ihinrere Paulu**

"Nipa agbara iṣẹ-àmi ati iṣẹ iyanu, nipa agbara Ẹmi Ọlọrun; tobẽ lati Jerusalẹmu ati yiká kiri ani titi fi de Illirikoni, mo ti wasu ihinrere Kristi ni kikun" (Romu 15:19). Bayii ni Paulu kọ iwe si Romu nigba ti o n rin irin-ajo kẹta ti itankalẹ Ihinrere yii. Illirikoni ti o ju bi ẹgbẹrun ibusọ ni ọgbọn-ọn ran lati Jerusalẹmu wà ni idabu okun lati Itali wá. Nigba ti o ti bẹ gbogbo ilu ti o wà ni agbegbe Jerusalẹmu ati Itali wò, ifẹ ọkan Paulu ni lati kọja lati Romu lọ si Spania ati awọn ilu ti o jinna siwaju. "Ṣugbọn nisisiyi bi emi kò ti li àye mọ́ li ẹkùn wọnyi, bi emi si ti fẹ gidigidi lati ọdún melo wọnyi lati tọ̀ nyin wá, nigbakugba ti mo ba nlọ si Spania, ng ó tọ̀ nyin wá" (Romu 15:23, 24).

Ninu awọn ọrọ diẹ wọnyii a ri ogunlọgọ ilẹ ti Apọsteli naa ti gba, sibẹ ọkan rẹ̀ n poungbẹ lati gba awọn ilẹ titun miiran fun Ihinrere. Ẹmi itankalẹ-ihinrere tootọ ni eyi ti kò mọ idaduro. Wahala oju ọna kò jẹ nnkan bi oun ba sa ti le waasu Kristi ki o si funrugbin Ihinrere si ilẹ titun ọlọra.

**Irin-ajo lati Efesu**

Lẹyin irukerudo nla ti Demetriu dá silẹ, Paulu fi Efesu silẹ o si mu ọna ajo rẹ̀ pọ̀n lati Makedonia lọ si Kọrinti ni Griki; bi ẹni pe o n pada sẹyin, o bẹrẹ si pada si Jerusalẹmu nibi ti o ti lero lati wọ ọkọ lọ si Romu. Nigba ti o kuro ni Efesu, ọ̀kan ninu awọn ilu ti o gbé duro ni Troasi. O wi bayii pe: "Nigbati mo de Troasi lati wãsu ihinrere Kristi, ti ilẹkun si ṣi silẹ fun mi lati ọdọ Oluwa wá, Emi kò ni alafia li ọkàn mi, nitoriti emi ko ri Titu arakọnrin mi: ṣugbọn nigbati mo ti dagbere fun wọn, mo rekọja lọ si Makedonia" (2 Kọrinti 2:12, 13). A gbagbọ pe ibi keji ti o tun ti duro ni Filippi nibi ti o ti kọ iwe keji yii si awọn ara Kọrinti ninu eyi ti o wi bayii pe: "Nigbati awa tilẹ de Makedonia, ara wa kò balẹ, ṣugbọn a

nwahalà wa niha gbogbo; ija mbẹ lode, ẹru mbẹ ninu. Ṣugbọn ẹniti ntù awon onirẹlẹ ninu, ani Ọlọrun, o tù wa ninu nipa didé Titu" (2 Kọrinti 7:5, 6).

### Iṣoro

Luku, ẹni ti o kọ Iwe Iṣe Awọn Apọsteli, kò mẹnu ba pupọ ninu awọn ohun ti o ṣẹlẹ, ṣugbọn ni ibẹrẹ iṣẹ-iranṣẹ Paulu, Ọlọrun ti wi pe, "Emi o fi gbogbo iya ti kò le ṣaijẹ nitori orukọ mi han a" (Iṣe Awọn Apọsteli 9:16). Igbesi-ayé Paulu Apọsteli ki i ṣe ọ̀rọ gbẹfẹ gẹgẹ bi o ti n fi ẹsẹ rin tabi wọ ọkọ oju-omi lati ibikan de ekeji. Iwe ti o kọ si awọn ara Korinti fi diẹ ninu awọn iṣoro ti o ba pade han ni. "Ará, awa kò sá fẹ ki ẹyin ki o wà li aimọ̀ nipa wahalà wa, ti o dé bá wa ni Asia, niti pe a pọ́n wa loju gidigidi rekọja agbara wa, tobẹẹ ti ireti kò tilẹ si fun ẹmi wa mọ́: Ṣugbọn awa ni idahùn ikú ninu ara wa, ki awa ki o máṣe gbẹkẹ le ara wa, bikoṣe Ọlọrun ti n ji okú dide: Ẹni ti o ti gbà wa kuro ninu ikú ti o tobi tobẹẹ, ti o si n gbà wa" (2 Kọrinti 1:8-10). Bi o tilẹ jẹ pe ikú doju kọ Paulu sibẹ o le wi pe, "Ipọnju wa ti o fẹrẹ, ti iṣe fun ìṣẹ́ju kan, o nṣiṣẹ ogo ainipẹkun ti o pọ̀ rekọja fun wa" (2 Kọrinti 4:17). "A npọn wa loju niha gbogbo, ṣugbọn ara kò ni wa; a ndãmu wa, ṣugbọn a kò sọ ireti nù. A nṣe inunibini si wa, ṣugbọn a kò kọ̀ wa silẹ, a nrẹ̀ wa silẹ, ṣugbọn a kò si pa wa run; Nigbagbogbo awa nru ikú Jesu Oluwa kiri li ara wa, ki a le fi iye Jesu hàn pẹlu li ara wa" (2 Kọrinti 4:8-10). Yoo ràn wá lọwọ lati gbagbe awọn idanwo ati aroye wa bi a ba mọ̀ pe awọn iyọnu wa wọnyii kò to nnkan bi a ba fi wọn wé eyi ti o dé bá aṣiwaju wa ninu Ihinrere yii.

Ronu awọn nnkan wọnni ti o ti la kọja, bi o ti n fi iṣẹ rẹ ṣe akawe pẹlu ti awọn eke apọsteli: "Niti lãlã lọpọlọpọ, niti paṣan mo rekọja, niti tubu nigbakugba, niti ikú nigbapupọ. Nigba marun ni mo gba paṣan ogoji din kan lọwọ awọn Ju. Nigba mẹta ni a fi ọgọ lù mi, ẹkanṣoṣo li a sọ mi li okuta, ẹ̃mẹta li ọkọ rì mi, ọsán kan ati oru kan ni mo wa ninu ìbú. Ni irin àjò nigbakugba, ninu ewu omi, ninu ewu awọn ọlọṣa, ninu ewu awọn ara ilu mi, ninu ewu awọn keferi, ninu ewu ni ilu, ninu ewu li aginjù, ninu ewu loju okun, ninu ewu larin awọn eke arakunrin; Ninu lãlã ati irora, ninu iṣọra nigbakugba, ninu ebi ati orùngbẹ, ninu àwẹ nigbakugba, ninu otutù ati ihoho" (2 Kọrinti 11:23-27). Dajudaju ki i ṣe ohun miiran bi ko ṣe imisi Ọlọrun ni o le mu ki eniyan tẹ̀ siwaju ninu igbesi-ayé ti o kún fún ewu ati wahala bẹẹ.

### Kọrinti

Lẹyin "ọ̀rọ iyanju pupọ" ni gbogbo ẹkùn Makedonia, Paulu wá si Griki, nibi ti o gbe ni oṣu mẹta pẹlu awọn ara Kọrinti ti o ti kọwe si. Bi o tilẹ jẹ pe Paulu ti jiya ohun gbogbo wọnni fun Kristi, sibẹ oun kò dakẹ lati maa waasu Ihinrere nigba ti o tilẹ jẹ pe o ti n sunmọ ẹni ọgọta ọdun, nitori nihin ni o kọ iwe rẹ̀ si awọn ara Romu ti o sọ pẹlu igbona ọkan pe: "Tobẹ̃ bi o ti wà ni ipá mi, mo mura tan lati wasu ihinrere fun ẹnyin ara Romu pẹlu" (Romu 1:15).

### Ọjọ Ikinni Ọsẹ

Dipo ki Paulu wọ ọkọ lati Kọrinti gẹgẹ bi eto ti o ṣe tẹlẹ ri, o rán awọn ọrẹ rẹ lọ si Troasi pẹlu ọkọ̀ nigba ti oun tikara rẹ fi ẹsẹ rin ibi ti o tó irinwo mile tabi ju bẹẹ lọ si Filippi, nibẹ ni o ti wọ ọkọ lọ si Troasi. Nihin, ni Ọjọ Oluwa, ti i ṣe ọjọ ikinni ọsẹ, awọn ọmọ-ẹyin pejọ. Ọjọ yii jé ọjọ ti awọn ọmọ-ẹyin maa n pamọ lẹyin ti Oluwa ti jinde, nitori Paulu paṣẹ fun awọn ara Kọrinti pe ki wọn mu ọrẹ wọn wá si ile Ọlọrun ni ọjọ naa. Jesu pẹlu, lẹyin ti O ti jinde ni owurọ Ọjọ Oluwa, O fi ara han awọn Apọsteli Rẹ̀ ni ọjọ yii ati ni Ọjọ Oluwa ti o tẹle e; nipa bayii Oluwa tikara Rẹ̀ fi aṣẹ si pipa ọjọ ikinni ọsẹ mọ́ dipo Ọjọ Isinmi awọn Ju. Awọn ọmọ-ẹyin ni Troasi pẹlu pa ilana Ase Ounjẹ Alẹ Oluwa mọ́ gẹgẹ bi Oluwa wa ti pa a laṣẹ.

### Awọn ti Ebi n Pa

Agbara nla Ọlọrun fi ara hàn ni Troasi nipa jiji okú dide. Lai si aniani ebi Ọrọ Ọlọrun ni lati maa pa awọn eniyan wọnyii, nitori pe Paulu waasu titi di ọganjọ, kò si da ẹnu duro ninu iwaasu rẹ̀ titi di afẹmọjumọ bi ko ṣe igba ti o mu ẹmi ọdọmọkunrin ni pada bọ̀. Lai fi aye silẹ fun isinmi, Paulu fi ẹsẹ̀ rin ogun mile lọ si Assosi. Boya Paulu ni itura gẹgẹ bi Jesu ti ni in nidi kanga Jakọbu nibi ti O ti bá obinrin ara Samaria ti ebi otitọ n pa pade.

**Ọrọ-iyanju Ikẹyin Paulu si awọn Alagba ni Efesu**

Iduro Paulu ni Efesu kò pẹ to bẹẹ, nitori ifẹ ọkan rẹ̀ ni lati wà ni Jerusalẹmu ni akoko ase Pẹntikọsti, ṣugbọn o ranṣẹ si awọn alagba, o si sọ ọrọ iyanju ikẹyin rẹ̀ fun wọn pe wọn ki yoo ri oju oun mọ. Ni fifi ara rẹ̀ ṣe apẹẹrẹ, Paulu gbà wọ́n niyanju lati jẹ́ onirẹlẹ ati oloootọ. O rán wọn leti pé Ẹmi Mimọ́ ni o fi wọn ṣe alabojutó, wọn si ni lati bọ́ ijọ Ọlọrun nipa sisọ gbogbo ipinnu Ọlọrun fun wọn. Ẹkọ Kristi ṣe pataki pupọ fun Apọsteli awọn Keferi yii, nitori o mọ̀ pe akoko yoo dé nigba ti awọn eniyan ki yoo le gba ẹkọ ti o ye kooro mọ́.

Paulu kò fẹ ki awọn ara Efesu yii fi ironupiwada silẹ. Boya oun ro ewu ti yoo dé bá awọn eniyan wọnyi nigba ti a ba n waasu pe ki awọn eniyan gba Kristi lai ni irobinujẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun fun ẹ̀ṣẹ wọn ati ironupiwada tootọ ki wọn si ni iyipada ọkàn. Oun kò fẹ ki awọn eniyan wọnyi ni ẹsin ti kò ni gbongbo lai ni Ẹjẹ Etutu ninu gẹgẹ bi o ti ri fun ọ̀pọ eniyan lode oni; nitori o rán wọn leti pe Ẹjẹ Jesu ni a fi ra Ijọ Ọlọrun. O tun wi pe Ọrọ Ọlọrun le gbé wọn duro ki o si fun wọn ni ini laaarin gbogbo awọn ti a sọ di mimọ́.

O ni lati di mimọ̀ fun Paulu pe awọn ikookò buburu yoo sọ ẹsìn di ọja tita, nitori naa o kilọ fun awọn alagba naa nipa ojukokoro. Jẹ ki ọwọ Paulu ti o ṣiṣẹ fun aini rẹ jẹ ibawi fun awọn wọnni ti n bẹbẹ fun fadaka ati wura ti wọn si n waasu Ihinrere fun ere ijẹkujẹ.

Lọsan ati loru fun ọdun mẹta, ikilọ ati omije Paulu ti fi ifẹ ati itara rẹ hàn fun awọn ara Efesu. Ifi tọkantọkan waasu Ọrọ naa han gbangba ninu ọ̀rọ rẹ ti o wi bayii pe: "Emi kò ti fà sẹhin lati sọ ohunkohun ti o ṣanfani fun nyin." Ẹmi Mimọ fi hàn pé ọ̀na ti o wa niwaju Paulu yoo mu ide ati ipọnju wa, ṣugbọn ọkàn rẹ̀ ti o duro ṣinṣin le dahun pe "Emi kò kà ẹmi mi si nkan rara bi ohun ti o ṣọwọn fun mi, ki emi ki o ba le fi ayọ̀ pari ire-ije mi, ati iṣẹ-iranṣẹ ti mo ti gbà lọdọ Jesu Oluwa, lati maa rohin ihinrere ore-ọfẹ Ọlọrun." Njẹ eyi ni ipinnu rẹ -- lati fori ti i titi de opin?

## AWỌN IBEERE

1 Gbiyanju lati ṣe awaari nipa awọn ọkunrin ti a darukọ wọn ninu Iṣe Awọn Apọsteli 20:4.

2 Sọ bi Paulu ṣe rin lati ilu dé ilu ninu ẹkọ wa oni.

3 Fi hàn lati inu Bibeli ifẹ ọkàn Paulu ati agbara rẹ̀.

4 Ibi meloo ni a ti ri i kà pe a ji okú dide ninu Bibeli?

5 Sọ pupọ ninu idi rẹ̀ ti a fi n jọsin ni Ọjọ Ikinni ọsẹ dipo Ọjọ Isinmi awọn Ju.

6 Ta ni yan awọn alàgbà Efesu ni alakoso?

7 Bawo ni Paulu ṣe duro pẹ́ tó ni Efesu?

8 Ọna wo ni Paulu gbà fi hàn pe oun kò ni ojukokoro?

9 Awọn koko ẹkọ Ọrọ Ọlọrun meloo ni a fi ẹnu ba ninu ori ẹkọ yii?

10 Sọ diẹ ninu awọn iya ti Paulu jẹ nitori Ihinrere.